**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbẹ l'ọrun gbọ. Ẹ o si mọ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.

# Irohin Yoruba

No. 815 JANUARY 18 — JANUARY 24, 1961 KOBO MEJI (2D)




# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE ṢE ISIN IDUPẸ IṢẸGUN

## Alufa kan saara si Awolọwọ o si sọ fun un wipe: Mura si otitọ rẹ ki o ma a se, Ọlọrun mbẹ lẹhin aṣ'ododo



OGUNLỌGỌ awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre lo wa sibi isin idupẹ ti Ẹgbẹ na se ni Ṣọọṣi "St. Saviour" ni Ikẹnnẹ Ijẹbu Rẹmọ ni ọjọ Aiku ti i se ọjọ kẹjọ oṣu yi. Nwọn ṣe isin na lati dupẹ lọdọ Ọlọrun fun Iṣẹgun Ẹgbẹ na ninu idibo yan aṣoju si Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, eyiti nwọn se ni ọjọ kejọ oṣu kẹjọ ọdun 1960. Ẹgbẹ Afẹnifẹre lo bori ninu idibo na. Ninu ọrọ iyanju ti Alufa to ṣe eto isin na sọ, o kan saara si Oloye Awolọwọ ti i ṣe Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn ọmọ Ẹgbẹ na yokù fun nkan ribiribi ti nwọn nṣe, o si ni ki nwọn mura si otitọ wọn lati ma a ṣe, nitoripe ko si bi o tilẹ pe to, otitọ ni yio leke. Aworan oke yi ni ti igbati awọn ọmọ Ẹgbẹ na nṣe isin lọwọ ni Ṣọọṣi. Wo oju ewe kẹjọ ati ikẹsan fun irohin isin na ati aworan yoku.

## Ibọn ọdẹ lo p'ọdẹ

ILORIN

LATI Apado, abule nla kan lẹba Ilọrin ni irohin ti o ṣeni laanu kan ti wa pe ọdẹ kan ku nibiti o ti nṣe wahala ŋkan ti yio jẹ.

Irohin na lo bayi pe nigbati ọdẹ na ti orukọ rẹ njẹ Sanu Ẹlẹmọṣọ ji ni owurọ kutu ọjọ Ru ti i se ọjọ kejidinlogbọn oṣu kejila ọdun 1960 nile rẹ ni abule Apado, o ki ibọn rẹ o kun, o si dorikọ ọna inu igbo lati lọ ṣe ọdẹ awọn ẹranko.

Nigbati o ti pẹ ti o ti nṣe wahala, ti nwọ inu igbo yi titi ti ko ri ẹran kankan pa, o wa pinnu wipe bi on ko ba ri ẹran pa, on yio kuku lọ pe awọn eso jijẹ ki on mu wọn lọ sile.

Bi o ti nlọ ni o taju kan, lo ba ri igi kan ti awọn ogẹdẹ so pupọ lara ẹka rẹ. Awọn ogẹdẹ na siti pọn nwọn si dara bi nwọn ti pọ to. O tara lọ si idi igi yi, o si gbe ibọn rẹ ti si ara igi na, lo ba bẹrẹ si ge awọn iti ogede na.

O ti ge awọn diẹ silẹ, njẹ ki o ge ẹyọ kan si ki on o to ma a lọ sile ni, bi o ti ge iti ọgẹdẹ na tan ni iti ọgẹdẹ miran ti ada rẹ ṣeṣi ba re lulẹ, o si bo lu ibọn ti ọdẹ yi ti kẹ silẹ. "Gba u" ni ibọn na ba yin, ó si yin ba ọdẹ yi, o ba ṣubu lulẹ lati ori igi ogẹdẹ.

(Wo oju ewe kẹrindilogun)

## Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ra Simẹnti Ewekoro

IBADAN.

NIBI aṣeyẹ kekere kan ti nwọn ṣe nile Gomina ni Ibadan ni ọjọ Iṣẹgun ti i ṣe ọjọ kẹwa oṣu yi, Ọba Alaiyeluwa Ọlọla Adesoji Aderẹmi Keji, Oni Ifẹ ti i ṣe Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun ra apo simenti akọkọ ti nwọn ṣe ni Ile Iṣẹ Simenti ni Ewekoro.

Ọlọla Gomina na san ṣile mẹwa fun apo simenti na. Ile Iṣẹ simẹnti na ni Ewekoro jẹ ti awọn ile iṣowo mẹta—"Western Nigeria Development Corporation." "West African Portland Cement Company" ati awọn "UAC" (oyinbo aladapọ).

Eto awọn alaṣẹ Ile Iṣẹ na ni pe nwọn yio ma a ṣe ọkẹ mẹwa tọnnu (200,000 tons) apo simẹnti lọdọdun. Ninu oṣu kejila ọdun ti o kọja ni nwọn ṣi Ile Iṣẹ na si Ewekoro. Aṣeyẹ iṣile iṣẹ na dun pupọ lọjọ na, irohin ko to afojuba ni.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Majẹkodunmi jẹ oye Ọdọfin Iyawo rẹ jẹ Lika

ABẸOKUTA

ESẸ gbogbo awọn enia ja-nkan ja-nkan lo pe sibi aṣeyẹ ifinijoye Ọlọla Dọkita M. Adekoye Majẹkodunmi, Minista Alamojuto Eto Akoso Iṣẹ Ẹgbẹ awọn Jagunjagun ati ọkan ninu Igbimọ Awọn Agba-Oṣelu Apapọ Ijọba Naijiria ni ọjọ Abamẹta ti i ṣe ọjọ keje oṣu yi. Nwọn fi jẹ oye Ọdọfin Ikereku Abẹokuta, nwọn si tun fi iyawo rẹ, Iyaafin Nora Majẹkodunmi, ọkan ninu Igbimọ Akoso Iṣẹ Ẹrọ Radio jẹ Lika Ikereku Abẹokuta ni ọjọ kanna.

Lati kutu owurọ ọjọ na ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọlẹbi idile ologbe Oloye J. B. Majẹkodunmi Ọtun Ẹgba Abẹokuta, ti iṣe Baba Oloye Ọdọfin titun na ti pe ṣoṣo si Ile Oloye na. Ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Minista Apapọ Ijọba Naijiria ati awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Naijiria mẹtẹta. Ọpọlọpọ awọn ọlọla ati Ọga Iṣẹ Ijọba ninu awọn oyinbo ati awọn oba, Ijoye, ọlọla ati gbajumọ wa lati Eko ati Ibadan ati yika gbogbo Naijiria pẹlu.

Ni agogo mẹsan ni Ẹgbẹ Afunfere Awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ Abẹokuta to siwaju, ti nwọn nfun fere gbogbo awọn alabaṣẹyẹ na si to tẹle awọn oloye pẹlu ọpọlọpọ ilu dundun, Aro ati Ṣẹkẹrẹ titi de Ile Ogboni Ikereku fun eto aṣeyẹ ifinijoye na. Bi nwọn ti wọ Ile-Ogboni na, awọn alugbẹdu ọẹrẹsi lu ilu gbẹdu awọn ọdẹ Ikereku ti ngyin ibọn kikan-kikan fun aṣeyẹ oye na, ni iṣoju gbogbo muju-muwa na ni Oloye Obe, Apena Ikereku ti ṣe ṣe etutu oye fun awọn oloye mejeji na, o sure fun wọn, o si de fila oye fun Ọdọfin titun na.

Lati Ile Ogboni na ni gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ti tun to tẹle wọn lọ si Gbọngan Apejọ Abẹokuta, fun aṣeyẹ ṣiṣi Ologbe Oloye J. B. Majẹkodunmi,

### AWORAN IRANTI

Bi nwọn ti de inu Gbọngan Apejọ Centenary ni nwọn bẹrẹ eto aṣeyẹ na. Ọlọla Ọba Alaiyeluwa, Ladapọ Ademọla Keji, Alake Abẹokuta ni o ṣe Alaga, ọmọ-Ọba Adedamọla, Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ẹgba si ni alakoso eto aṣeyẹ na. Lẹhin adura ṣiṣi ipade aṣeyẹ na, ọmọọba Adedamọla sọ ọrọ iṣiri pupọ nipa igbesi-aiye ologbe oloye J. B. Majẹkodunmi, Ọtun Ẹgba ti nwọn nṣi aworan iranti rẹ lọjọ na. Oloye Kashimawo si gbe ọrọ rẹ lẹsẹ nipa sisọ itan iṣẹ-iṣowo ologbe na lati ọdun de ọdun ni ilu Ẹgba ati gẹgẹbi o ti jẹ enia pataki ati oninu rere to.

Lẹhin eyi, o tun ka Iwe Ikini ku-orire ti awọn Ẹgbẹ Igba-ewe oloye Ọdọfin na fi ta a lọrẹ si etigbọ gbogbo enia, Oloye Ọdọfin na si dupẹ pupọ lọwọ wọn ati gbogbo enia nigbati o nfesi si ọrọ ikini-ku-orire na. Bi nwọn ti pari eyi ni Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Alake Abẹokuta ba ṣi Aworan Iranti na lẹhin ọrọ iyanju diẹ ati adura.

Ẹṣin dudu kan ni oloye na fi ya aworan na ni igba aiye rẹ, ẹnikẹni si ri ọrọ ka ninu aworan na pe, ọdun mẹtalelogoji (1910-1953) ni Oloye na fi wa ninu Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ẹgba, o si ku nigbati o di ẹni ọdun mẹtadiladọrun (87 years) laiye. Ni owurọ ọjọ keji, ti i ṣe ọjọ Aiku, oloye Ọdọfin ati gbogbo awọn ẹbi ologbe oloye J. B. Majẹkodunmi ṣe isin idupẹ ni Ṣọọṣi Ikereku (Holy Trinity), Alufa Oshinowọ lo si ṣe e to isin na.

## Aara pa ẹnikan si ẹnu ọna Mọṣalaṣi

IGBO-ỌRA

LAIPẸ yi ni Aara san pa ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Amuṣa Alabi ni ẹnu ọna Mọṣalaṣi kan ni ilu Igbo-Ọra, nwọn si ti gbe oku rẹ lọ si lakulaku Ile-Iwosan Adeọyọ, Ibadan fun ayẹwo.

Irohin ti ọkan ninu awọn ẹbi ẹniti Aara pa na ṣe fun awọn ọlọpa ni pe, lati Abẹokuta ni awọn mejeji ti wa ṣe inawo isinku kan ni Igbo-ora ki aara to san lu u ni iwaju ori rẹ ti o si pa a.



# Itan işędalę ilu Ọyọ

### Lati ọwọ Akindele, Ọyọ




MO dupę lọwọ Olotu fun aye ti o gba mi lati sọ itan ilu mi Ọyọ fun gbogbo aiye ka ninu Iwe "Irohin Yoruba" mo si fi eyi kęwọ lati juba fun gbogbo awọn agba-opitan yika gbogbo Itan na lọ bayi:-

Ilu Ọyọ jẹ pataki ati olokiki pupọ larin gbogbo ilu ti o wa ni ilę Yoruba, ọmọ Oba Oduduwa ni Ile-Ife ti orukọ rę nję Oranmiyan ni o tę ilu na do si eti ibikan ti orukọ rę nję Igbetti, awọn ara Ọyọ si şipopada kakiri lati ibę ki nwọn to wa tędo si ibiti ilu Ọyọ wa loni.

**ỌYỌ ILE**

Ibiti nwọn kọkọ tę ilu Ọyọ do si ni nwọn npe ni Ọyọ-Ile. ni akoko na, Ọba ti o wa ni adugbo na ti orukọ rę nję Olowu nikan ni Ọba. Nigbati Ọba Ilọrin nfę gba ilę lọwọ Ọlọyọ ni ogun ba bę silę, nwọn ja ogun na fun ọpọlọpọ ọdun şugbọn ni ikẹhin, awọn ara Ilọrin ni o şegun. nwọn si le wọn kuro ni Ọyọ-Ile.

Nigbati nwọn si kuro nibę, nwọn lọ tędo si Ọyọ-Aga. Ọba Olowu kanna si tun ni Ọba fun gbogbo wọn. A gbọ wipe ọpọlọpọ Ọba ni o jẹ tęlę ara wọn ni Ọyọ-Aga, şugbọn lẹhin ọdun diẹ si i, awọn enia ko ni itęlorun si ibę mọ nwọn si pinnu lati fi ibę silę lọ si Kobaiye.

Nigbati awọn ara Ọyọ şipopada de Kobaiye, nwọn ko ri omi rara, omi sọwọn pupọju ni ilu na, ko tilę si odo-şişan tabi adagun-omi kankan ni gbogbo gbegbe ilę na.

Nitori idi eyi, Olowu ti o jẹ Ọba si paşę fun awọn ęmęwa rę pe ki nwọn gbę kanga awọn enia na • si gbę ọpọlọpọ kanga, sibęsibę na, nwọn ko ri omi lati fun awọn enia wọn mu. Bi enia ba si de ilęto na loni, yio ri ọpọlọpọ ninu awọn kanga ti nwọn gbę nigbana. Nigbati wọn ko tun ri itęlorun nibę, ni nwọn ba tun şe ipinnu lati si kuro, nwọn si tun şi lọ tędo si Ọyọ Igboho.

**ILẸ ỌLỌRA**

Ilę ọlọra ti o dara pupọ fun nkan ọgbin ni ilę ilu Igboho. Orişirişi odo-şişan ati adagun-omi wa nibę pęlu, awọn ara Ọyọ si ri itęlọrun pupọ nigbati nwọn şi de ibę lati Kobaiye nwọn ngbin orişirişi ohun ọgbin, bi işu. agbado, ọkababa, ęgusi ati bę ę lọ, awọn enia si nri onję pupọ je, ko si ebi, ko si si iyan.

Nipa bę ę, nwọn roju, nwọn si raye lati tun ilu wọn şe. Oluewu lo jẹ Ọba fun awọn Ọyọ ni akoko na, o si yan awọn Ijoye meje, o pe orukọ awọn Ijoye na ni "Ọyọ-Misi".

Orukọ ti Ọba Oluewu fun awọn Ijoye Ọyọ-Misi meje na ni (1) Bashọrun (2) Agba-Akin; (3) Lagunna; (4) Alapinni; (5) Shamu; (6) Ọnamọdękę ati (7) Akinniku.

Işę ti o yan wọn fun ni lati ma a ba a şe akoso ilu. O şeni laanu pe, ilu Igboho yi ni Ọba Oluewu na ku si, şugbọn o bi ọmọkunrin kan nibę, o pe orukọ rę ni Abiọdun Atiba. Nigbati ọmọ yi dagba, o di gbajumọ ati ayanfę enia fun gbogbo ara ilu Ọyọ-Igboho, nitori idi eyi, gbogbo enia gba wipe on ni ki nwọn fi jọba rọpo babarę (Oluewu) ti o waja.

**ỌBA ATIBA**

Lẹhin ti nwọn ti pinnu lati fi ọmọ-ọba Abiọdun Atiba jẹ Ọba lẹhin iku baba rę, Ọba Oluewu, Abiọdun Atiba si gba awọn enia rę ni imọran pe ki nwọn jęki awọn şi kuro ni ilu na lọ si ilę ibomiran, nwọn si gba fun un.

Bayi ni awọn enia Ọyọ ba fi tun şi kuro ni Igboho, ti nwọn si tun wa tędo si ilu Ọyọ ti nwọn wa nisisiyi. Diẹ ninu orukọ awọn agbo-ile ati ọja ti o wa ni ilu Ọyọ nisisiyi ni o tun wa bakanna bę ę ni ilu atijọ Igboho na titi di isisiyi.

Nigbati awọn ara Ọyọ si kuro ni Igboho de Ọyọ ti nwọn wa nisisiyi, awọn ọkunrin meji kan ti nwọn jẹ tęgbọn-taburo ti nwọn nşe işę ọdę orukọ ekini nję Ọja orukọ ekeji si nję Ęlębu ni nwọn ba lọri ilę Ọyọ ti nwọn tędo sibę ti nwọn si nşe ọdę apęran kakiri inu igbo agbegbe adugbo na.

Ọja ni ęgbọn fun Ęlębu, on ni o si ni gbogbo ilę Ọyọ jagun-jagun si ni awọn ọdę mejeji na pęlu. Nigbati gbogbo ọran na jẹ bayi, ni Atiba ba fi ọgbọn-ęwę ba Ọja da imọran kan papọ pe, ki Ọja jęki on ati awọn enia on ma a ba wọn gbe papọ lori ilę wọn na. O si şe ileri fun un pe, awọn yio ma a ran lọwọ dada ni akoko ogun Ọja si gba imọran Atiba na, o ni on fi ara mọ o ki nwọn jọko ti on ati aburo on.

**OGUN GBODO**

Ko pę pupọ lẹhin eyi ni ogun nla kan ti nwọn pe ni ogun Gbodo bę silę larin ilę Yoruba, Ọja, Ęlębu, Atiba ati gbogbo awọn enia rę si lọ si ogun na. Ọja ni ojulowo oogun egbe kan ti o ma a nran an lọwọ lati le pada wa sile bi ogun ba fę buru fun un, şugbọn lọwọ iyawo rę ni oogun yi ma a ngbe. Iyawo rę a si ma a lo o fun un nile bi ọkọ rę Ọja, ba wa loju ogun lọhun.

Nigbati nwọn bęrę ija ni oju ogun Gbodo na, Ọja fi gbogbo agbara rę ati iranlọwọ oogun rę ja ogun na, o si şegun. Nigbati gbogbo awọn enia wa ndari ti ogun na bọ wa si Ọyọ, nwọn kan odo nla kan, ọkọ ni nwọn fi ntu awọn enia kọja si odi-keji lori rę.


Aworan oke yi ni ti Ọba Alaiyewuwa Gbadegęshin Ladigbolu Keji, Alafin Ọyọ nigbati nwọn yan an ni Alafin.

(wo oju ewe kọkanla)

# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE ṢE ISIN IDUPẸ TI IṢẸGUN NI ṢỌỌṢI IKẸNNẸ

## AWO ATI IYAWO RẸ SE ASE NLA FUN AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ NA





## Awọn Ọlọṣa mẹta gba idajọ iku

E mọ o ka iwe IROHIN YORUBA nigbogbogbo fun irohin aladun




DA INU-RIRUN DURO



"MILK OF MAGNESIA"

PHILLIPS


## AKIYESI PATAKI

### ITUMỌ ALA

OLOTU



## ABIMBỌLA JẸ OYE

## Adajọ sọ Edi si ẹwọn oṣu mejila

## Ijoba Ibilẹ Ibadan fẹ kọ ọja titun si Gẹgẹ

IBADAN


IṢAKA, AWỌ-ARA TI KO LẸWA FẸRẸ BA AYỌ-ỌMỌGE RẸ JẸ





MENTHOLATUM CO. LTD

MENTHOLATUM

